# Ìyiri Ìwọ́ká Ìran Yorùbá Wò Nínú Àṣàyàn Fíìmù Àgbéléwò

**Prof. Dúró Adélékè**
*Department of Linguistics and African Languages*
*University of Ibadan, Ibadan*
*duroadeleke@yahoo.com*

## Àṣamọ̀

Àkíyèsí tí a ṣe ni pé bí àwọn ẹ̀yà ìran ènìyàn ṣe ń wọ́ káàkiri ilẹ̀ ayé ni ìran Yorùbá náà wọ́ kiri. A rí èyí wò nínú ọ̀pọ̀ fíìmù àgbéléwò Yorùbá . Kí a ba lè mọ àwọn nǹkan tí ó ń bí ìwọ́ká yìí, a fi ìmọ̀ eékì ìṣe-kárí-ayé ṣé àtẹ̀gún fún iṣẹ́ ìtúpalẹ̀ yìí. A sì ṣàmúlò fíìmù márùn-ún kan tí a mọ̀-ọ́n-mọ̀ ṣàyàn: *Odùduwà, Jógunómí, Àyàn Àgalú*, *Àfọ̀njá* àti *Àbẹ̀ní*._ Ẹ̀rí tí a rí gbámú fi hàn pé ọ̀wọ́ fọ́nrán gbédìí gbédìí méjì gbòógì ni ó ń fa ìwọ́ká: fọ́nrán gbọ̀n-ọ́ngbọ̀n-ọ́n àti fọ́nrán òǹfà. Ṣùgbọ́n ọ̀kọ̀ọ̀kan àwọn fọ́nrán yìí ni ó ní àkóónú ọmọlẹ̀ tirẹ̀.

**Kókó Ọ̀rọ̀:** Fíìmù àgbéléwò, ìwọ́ká, ìṣe-kárí-ayé, fọ́nrán gbọ̀n-ọ́ngbọ̀n-ọ́n, fọ́nrán òǹfà.

**Ìfáárà:**

Ká tó pabì, ká tó yàbìdun ohun tí a fẹ́ sọ̀rọ̀ lé lórí, ó tọ́ ó yẹ́ kí á yán àwọn nǹkan kan. Ìyánrọ̀ fẹ́rẹ́ ni a o fi àwọn ọ̀rọ̀ náà ṣe. Ohun tí ó jẹ wá lógún nínú iṣẹ́ yìí ni ìyiri wò ìwọ̀ká ìran Yorùbá láti ìlú kan dé ìlú kan, tàbí láti orílẹ̀-èdè kan sí orílẹ̀-èdè mìíràn. A fẹ́ wá fìn-ín-ìn ìdí kókò tí o máa ń mú ọmọ níbi-níran dèrò ilẹ̀ mìíràn. Orísun àwọn èròjà pépà yìí ni àwọn fíìmu àgbéléwò *Odùduwà 1 àti 2, Àfọ̀njá, Àyàn Àgalú, Jógunómí* àti *Àbẹ̀ní* 1 àti 2. A wo àwọn fíìmù yìí láti le ṣe àwárí àwọn ẹ̀rí ọ̀rọ̀ tí kìí jẹ́ kí ọmọ Yorùbá gbé ilé. A tún ṣe àyẹ̀wò àwọn àkọsílẹ̀ díẹ̀ nínú àwọn ìwé kan.

Kí iṣẹ́ yìí ba à lè rọrùn fún wa, a lo àwọn àkòrí ọ̀rọ̀ olóórí-jorí: Ìwọ̀ka ẹ̀dá ọmọ ènìyàn gẹ́gẹ́ bí ó ṣe hànde nínú tíọ́rì ìṣekárí-ayé, ìwọ̀ká onífọ̀nrán gbọ̀n-ọ́ngbọ̀n-ọ́n àti ìwọ̀ká onífọ̀nrán òǹfà.

**Ìwọ̀ká ẹ̀dá ọmọ ènìyàn**

Lóòótọ́ ni Yorùbá bọ̀ tí wọ́n sọ pé: Ibi a bá fi iyọ̀ sí ní ṣomi sí àmọ́ ọ̀rọ̀ ìjìnlẹ̀ yìí kò fi tara tara ṣe bẹ́ẹ̀ mọ́yán-lórí tí a bá ṣe àwòmọ́-ọn rẹ̀ pẹlu ìlọsíwá, lọ-sókè lọ-sódò ọmọ ènìyàn. Gbédìí gbédìí jọ̀kan lára àwọn nǹkan wọ̀n-ọnnì tí máa ń dàámú ọmọ ènìyàn. Ó wá yẹ ká bira wa léèrè àwọn nǹkan tí ń fa gbédìí gbédìí fún ẹ̀dá ọmọ ènìyàn láyé àtijọ́ àti láyé òde-òní ti wọn fi í kúrò nílé tàbí tí wọ́n fi í di àárè òun àtìpó nílẹ̀ mìíràn.

Bí Yorùbá ti sọ, "Ọba kì í pé méjì láàfin", ìjòyè lè pé mẹ́fà láàfin. Bí a kò bá gbàgbé, Odùduwà bí Ọ̀kànbí, Ọ̀kànbí bímọ méje. Kóówa ọ̀kọ̀ọ̀kan àwọn ọmọ wọ̀nyí ni adé Odùduwà tọ́ sí. Níwọ̀n ìgbà tí ó sì tí jẹ́ pé kò síbi tí kò gbògo, àyàfi ọ̀lẹ nìkàn làyè ò gbà; àwọn ọmọ-ọmọ Odùdùwa ń wá ilẹ̀ ọ̀tun tẹ̀dó, kí àgbò méjì má baà mumi lákoto. Ohun tí à ń sọ ni pé ọ̀rọ̀ ìṣèlú tí ó jẹ́ mọ́ ọ̀rọ̀ lọ́balọ́ba ló mu àwọn ọmọ Yorùbá kan fi ìlú wọn sílẹ̀ pẹ̀lú àwọn agbọ̀ràndùn wọn.

Nǹkan mìíràn tí ó tún fa sábàbí ìwọ́ká ni ọ̀rọ̀ ogun jíjà láàrin ìlú kan àti òmíràn. Bẹ́ẹ̀ rèé ogun kòríbí iyán, ogun kò rí bí ẹ̀kọ, ogun kò sì dàbí ká sùn taya ẹni níyẹ̀wù. Ogun ti kó àìmọye ìlú. Àwọn ẹni-orí-kó-yọ ni wọ́n ṣàtìpó nílẹ̀ àjòjì. Abájọ tí Yorùbá fi sọ pé: Bí Ìlá kò bá gbeni, a máa kọrí sí Ìlalà. Àwọn mìíran tí ogun kó ni wọ́n mú tà lẹ́rú sí àwọn ìlú mìíràn àti sí ilẹ̀ òkèèrè pàápàá Kuba (Cuba), ilẹ̀ Amẹ́ríkà (Akintoye 2010; Falọla 2012). Ẹ̀wẹ̀, nǹkan mìíràn tí ó tún ti ọmọ ènìyàn kiri ni iṣẹ́-ajé. Ọ̀rọ̀ okòwò máa ń gbéni kiri ni, nípasẹ̀ bẹ́ẹ̀ ni àwọn kan fi dèrò ilẹ̀ mìíran. Wọ́n gbà pé ibi orí dáni sí là á gbé. Wọ́n sì bẹ̀rẹ̀ sí dirún digba.

Bí ó tílẹ̀ jẹ́ pé ọ̀rọ̀ ogun abẹ́lé, ìjà, ìpórógan àti iṣẹ́-ajé sì jẹ́ ara àwọn nǹkan tí ń bí ìwọ́ká ẹ̀dá ènìyàn láyé òde-òní bi ti àtijọ́, Okome (2005) náà tọ́ka sí i pé àwọn nǹkan mìíràn tí ó tún bí ìwọ́ká àti ìtúká ni ìsanwó ọ̀yà tásọ́rẹ́ fún ni, àìríṣẹ́-ṣe, àìsí-ní-ilé àwọn ẹbí ẹni pàápàá àwọn tó ti bọ́dìí sí ilẹ̀ mìíran, ìfọjọ́-gbogbo fojú winá-ogun àti ìtẹnimẹ́rẹ̀ láwùjọ ẹni. Èyí jẹ ará

nǹkan tí ó ń bí títa-tẹ̀tẹ̀-ìwé-ìrìnnà-ìgbélùú ilẹ̀ Àmẹ́ríkà tí ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn ọ̀dọ́ ọmọ ilẹ̀ Áfíríkà kó-gìírì mọ́. Wọn gbàgbé pé ọ̀nà ìsọra-ẹni-dẹrú ẹlẹ́ẹ̀kejì ni èyí. Ọ̀rọ̀ ń bọ̀ lórí eléyìí lọ́jọ́ iwájú, a kò fẹ́ fi ẹ̀tẹ̀ sílẹ̀ máa pa làpálàpá. Ní ṣókí ohun tí à ń sọ ni pé ẹ̀ṣẹ́ ló ṣẹ́ àjànàkú kí a tó rí erin rà lórí àtẹ ni ọ̀rọ̀ ìwọ̀ká àti ìtúká ìlú jẹ́. Bí ẹ̀dá kan bá sì ń lọ sílẹ̀ ọ̀tun, ó di dandan kí ìṣe ilé bá a dé òde, kí òun náà sì ṣe àgbàmọ́ra ìṣe òde.

Okome (2005) ní nǹkan méjì gbòógì ni ó máa ń ṣe okùnfà ìwọ̀ká tàbí ìtúká. Àwọn náà ni "fọ́nran Òǹfà" àti "fọ́rán Gbọ̀n-ọ́n-gbọ̀n-ọ́n". Ó ṣàlàyé síwájú síi pé:

> Push factors usually create the desire to emigrate while pull functions provide the opportunity to act that desire (Okome 2005:86).
>
> Àwọn fọ́nrán gbọ̀n-ọ́ngbọ̀n-ọ́n máa, ń sàbà fi ààyè gba àníyàn náà láti jáde nílùú nígbà tí àwọn fọ́nrán òǹfà fi àǹfààni sílẹ̀ láti gbé ìgbésẹ̀ lórí àníyàn náà.

Àwọn ọmọlẹ̀ tí a lè tò sábẹ́ fọ́nrán gbọ̀n-ọ́ngbọ̀n-ọ́n ni ogun abẹ́lé, ìbẹ́sílẹ̀ àjàkálẹ̀-àrùn, ìdúnkokò-mọ́nì, àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ Àwọn ọmọlẹ̀ tí ó wà lábẹ́ fọ́nrán óǹfà ni: didara pọ̀ mọ́ ẹbí ẹni, iṣẹ́ òòjọ́, àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

Ní ti Akintoye (2010) ó fi hàn pé nǹkan méje ni ó ń fa gbédìí gbédìí fún ìran Yorùbá. Lára nǹkan méje tí ó mẹ́nu bá ni títẹ̀lé ìmọ̀ràn Ifá. Babaláwo tí orúkọ rẹ̀ ń jẹ́ Agírílọ́gbọ̀n, tí ń gbé

Ìta Asìn ní Ilé-Ifẹ̀ ló dífá nígbà tí ìyàn mú gan an, tí àwọn èèyàn tún wá pọ̀ ní ìpọ̀ yábá. Ó wá ṣàlàyé pé Ifá gba ìlú ní ìmọ̀ràn pé kí àwọn ènìyàn kan fi ìlú sílẹ̀. Àwọn èèyàn kan sí ṣe bẹ́ẹ̀, wọ́n tẹ̀lé ìmọ̀ran Ifá. Wọ́n wá lọ wá ìlú mìíràn tẹ̀dó sí. Ìfẹ̀hónúhan tún jẹ ọmọlẹ̀ mìíran tí ó bí ìtúká tàbí ìwọ́ká. Ọbawinrin jẹ́ ọ̀kan lára àwọn tí ó ti wà ṣaáju Odùduwà, ó sì jẹ́ ọ̀kan lára àwọn ọba tó ní igun tirẹ̀ ní Ilé-Ifẹ̀. Ìjà tó wà láàárín Odùduwà àti Ọbàtálá ló fà á tí ó fi fi ìlú sílẹ̀, tí ó sì lọ dá Ìjọ Ìgbò-Ìgbò silẹ̀ (Akintoye 2010:89).

Nǹkan kẹta ni pé tí ìyàn bá tí mú àwọn mìíràn máa ń fi ìlú sílẹ̀ bi a ti sọ ṣaájú. Ọ̀rọ̀ ijà oyè máa ń mu àwọn ọmọ-ọba tí kò róyè jẹ ṣí kuro ni ìlú wọn. Púpọ̀ irú àwọn ọmọ oyè bẹ́ẹ̀ ni wọ́n máa ń rọ́wọ́ mú ní ilẹ̀ àjèjì tí wọ́n ṣì lọ. Ẹ̀wẹ̀, nígbà tí ìjọba Yorùbá bá tànmọ́-ọ̀n pé agbo ìṣèjọba wọn ti fẹ́ kọjá àlà, níṣe ni wọ́n máa ń ṣe onígbọ̀wọ́ ìdásílẹ̀ ìjọba titun. Akintoye (2010) sọ pé ìjọba alágbára Ọ̀yọ́-Ilé ṣe ìdásílẹ̀ àwọn ijọba mìíràn bí ilẹ̀ Ọ̀yọ́, Ẹ̀gbádò àti Ìgbómìnà, Ẹdẹ, Ọ̀fà, Ìgbàjà (o.i 90).

Ìfayé-nini-lára nínú ètò ìṣèjọba àwọn alámùúlégbè-ẹni máa ń fa sábàbí ìṣípòpada. Àpẹẹrẹ tí a rí láti inú ìwé Akintoye (2010:90) ni pé, ìninilára àwọn ọmọ ogun Iléṣà ló fa ìdásìlẹ̀ ìjọba Ìmẹ̀sí-Ìgbódó (Oke-Mẹ̀sí), ní ilẹ̀ Èkìti. Àwọn tí wọ́n fi ìlú Ìmẹ̀sí-Ilé sílẹ̀ ni wọ́n dá a sílẹ̀. Àmọ, àwọn gbajúmọ̀ ìlú tí wọ́n ní jọ̀bọ̀jọ̀bọ̀ lápá, tí wọ́n sì tún ní òye máa ń mọ̀-ọ́n-mọ̀ ṣe ìdásílẹ̀ ìlú tàbí ìletò sínú igbó. Wọ́n á ṣe kẹ̀rẹ̀ kẹ̀rẹ̀ máa kó àwọn ènìyàn

mọ́ra, àtonílé àti àlejò. Nígbà ti bùdó titun náà kò bá tí gbọ̀rẹ̀gẹ̀jigẹ̀, elú ni wọn máa ń pè é (Akintoye 2010:91).

Àkíyèsí tí a ṣe ni pé àwọn ọmọlẹ̀ méjèèje tí Akintoye ṣe àgbékalẹ̀ ni a lè pín sí ọ̀wọ́ méjì gbédìí gbédìí tí Okome (2005) fi lélẹ̀. Nítorí náà àwọn ọmọlẹ̀ tí ó ń bí gbédìí gbédìí tí Okome, Akintoye àti Fálọla mẹ́nu kan ni a kó jọ pọ̀ sí abẹ́ àtẹ ìṣàlẹ̀ yìí

| Fọ́nrán Gbọ̀n-ọ́ngbọ̀n-ọ́n | Fọ́nrán Òǹfà |
|---|---|
| - Ìmọ̀ràn Ifá | - Iṣẹ́ ìgbọ̀wọ́ onírọ̀rùn |
| - Ìfẹ̀hónúhàn/ìrúnú | - Fifi ìrọ̀rùn dá elú sílẹ̀ |
| - Ìyàn mímú | - Idarapọ̀ mọ́ ẹbí ẹni |
| - Ìjà oyè láàárín àwọn ọmọ oyè | - Iṣẹ́ òòjọ́ |
| - Ininilára | |
| - Ìmúnilẹ́rú | |

Àwọn fọ́nrán tí a là kalẹ̀ yìí ni ó mú wa láti mẹ́nu kan ọ̀rọ̀ àṣà.

A ti sọ̀rọ̀ nípa iṣẹ́ ogun àwọn Oníkòyi lẹ́ẹ̀kan, ṣùgbọ́n mo tún fẹ́ ṣe àmúlò ìlà bí mélòó kan láti fi fa kòmóòkun ọ̀rọ̀ kan yọ lórí ìtàn àti àṣà.

Ogun ló burú
L'Ẹ̀ṣọ́ ò délé pé
Ogun ló le
L'Ẹ̀ṣọ́ ò pera wọn lóókọ (Babalọlá 2001)

Ó yẹ kí a wá bí ara wa léèrè pé kín ni ó fà á tí àwọn ẹ̀ṣọ́ kò fi délé pé?

Ẹ̀ṣọ́ kò délé pé nítorí pe lára wọn ti bógun lọ. Ẹ̀ṣọ́ kò délé pé mọ, nítori pé nínú wọn tí di aláàbọ̀ ara. Parí parí ẹ, ẹ̀ṣọ́ kò délé pé mọ́ nítorí tí wọ́n tí kọ́ ìṣe àti àṣà àwọn tí wọ́n tí bá jagun. Bí àwọn ènìyàn kọ̀ọ̀kan bá tí ń sí kúrò láti ibìkan sí ibòmíràn, àṣà tí wọn mú kúíò ni ìlú wọn á wà nínú ẹ̀jẹ̀ wọn, pàápàá àṣà àìjẹmọ́-ohun-èlò. Àṣà àìjẹmọ́-ohun-èlò náà ni èdè, ẹ̀sìn, òfin, ewì alohùn àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Kì í ṣe pé àṣà àjẹmọ́ ohun-èlò kọ̀ọ̀kan a di ìgbàgbé o, ṣùgbọ́n kì í ṣe gbogbo rẹ̀ ló ṣe é gbé kúrò nílé. Ẹ̀wẹ̀, ẹni tí ogun mú tó dẹrú, kò le rójú ráàyé ko àwọn àṣà ajẹmọ́ -ohun-èlò dání. Àmọ́, Akintoye (2010) àti Falọla (2012) fi ohùn sọ̀kan pé àṣà Yorùbá, pàápàá èyí tó jẹ mọ́ èdè, ẹ̀sìn, ìbọ àti oúnjẹ Yorùbá rí ẹsẹ̀ walẹ̀ ní Ìwọ̀-Oòrùn ilẹ̀ Áfíríkà àti ní ilẹ̀ Àmẹ́ríkà.

Ìsípòpada kúrò ní orírun wọn máa mú àyípadà bá ìtàn ìgbésì ayé wọn. Tí èyí bá ti sẹlẹ̀, ẹ̀tọ́ ni kí a fi iṣẹ́ yìí kọ́ tíọ́rì ìṣe-kari-ayé lọ́rùn. Èyí ni ó sì fa sábàbí tí a o fi máa mú lárá àwọn ọmọlẹ̀ tí ó rọ̀ mọ́ eékì ìṣe-kárí-ayé bí ìṣàtatòpò àṣà, ìwà, ẹ̀sìn, èrò àmójúwáyé, àti ìṣe adíkálà. Ti àwọn ọmọlẹ̀ wọ̀nyì ba ti fara han a jẹ́ pe a ti tàtaré dé agbọn tíọ́rì aṣàtakò ìmúnisìn nù un. Adeleke (2011) sọ pé:

> Àwọn wúnrẹ̀n àkóónú tíọ́rì aṣàtakò ìmúnisìn mìíràn ni ìṣàtìpó ní ilẹ̀ àjèjì, ìsọ-nǹkan-ẹlòmíràn-di-tẹni, ìṣe bàràǹdà àti nínú àwọ̀ adikálà. Ìṣàtìpó jẹ mọ́ gbígbé ní ilẹ̀ òkèérè yàtọ̀ sí ilẹ̀ ẹni. A lè ṣe èyí nípa ìfẹ́ ẹni, tàbí kí nǹkan fi ipá mú ni lọ ṣe àtípó nílẹ̀ mìíran. Ẹ̀wẹ̀,

ìṣọ-nǹkan-ẹlòmíràn-di-tẹnì í sàpèjúwe bí àwọn àwùjọ tí wọ́n ti dòmìnira ṣe ń sọ àṣà ìjọba amúnisìn di ti ara wọn.

Ohun tí à ń ṣọ yóò fojú hàn ketepe nínú iṣẹ́ ìtúpalẹ̀ yìí.

## Ìwọ̀ká Onífọ́nrán Gbọ̀n-ọ́ngbọ̀n-ọ́n

Gbogbo àwọn ọmọ Yorùbá tí wọ́n kó lẹ́rú lati Ìbàdàn lọ sí Ìjẹ̀bú kò fi ìrọ̀rùn lọ. Ipá ni àwọn ọmọ-ogun Ìjẹ̀bú fi mú wọn lẹ́rú, bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé wọ́n tún fẹ́ lára àwọn ẹrúbìnrin tó bá yáyì ní ìyàwó. Ohun tí a wí yìí fi ara hàn dáadáa nínú fíìmù àgbéléwò *Jógunómí.* Ìtúkáa àpàpà- ń-dodo ni èyí. Àwọn Ìbàdàn náà tún padà mú lára àwọn Ìjẹ̀bú lẹ́rú o. Èyí fi hàn pé níjọ́un àná, àwọn ẹ̀yá Yorùbá kan tí wọn ń gbógun ti ará wọn máa fipá mú ẹ̀yá kejì lẹ́rú lójú ogun wọ ìlú wọn.

Ọba ìlú le è fi tipátipá fi àṣẹ ọba lé ènìyàn kúrò ní ìlú, ó sì le è lé ẹgbẹ́ kan kúrò. Irú fíìmù *Àyàn Àgalú*, níbi tí ọba Adérìnọ̀lá ti lé àwọn ẹgbẹ́ onílù tí wọ́n fi orò *Àyàn Àgalú* gbé lórí ìwá ìbàjẹ́ tí ó hù nípa pípa ọkọ obìnrin tí ó fẹ́ fẹ́. Bàyìí ni àwọn onílù ṣe fi ìlú Alákùkọ sílẹ̀ lọ́ sí Arẹ́gbẹ́ọmọ. Àwọn ará ìlú Arẹ́gbẹ́ọmọ kò nílù tí wọn fi í ṣe àríyá, pẹ̀ẹ̀pẹ́ ni wọ́n fi ń lu ara wọn. Ìlù tí àwọn ẹgbẹ́ onílù láti Alákùkọ lù ni wọ́n fi dẹni tí ọba Arẹ́gbẹ́ fi gbà wọ́n tọ̀wọ́ tẹṣẹ̀.

Ẹ̀wẹ̀, ènìyàn lè jẹ́ àjèjì ní ilẹ̀ mìíran kí fọ́nrán gbọ̀n-ọ́ngbọ̀n-ọ́n tún tì í kúrò níbẹ̀ gẹ́gẹ́ bó ṣe ṣẹlẹ̀ sí Bàbá Rọ́pọ̀, tí wọ́n lé kúrò ni ìlú Ìbàdàn nítorí ìwà aṣe-máṣe tí ọmọ rẹ̀ hù. Rọ́pọ̀ yan

ìyàwó Abídogun tí í ṣe ọ̀kan nínú àwọn olórí-ogun Ìbàdàn lálè. Bàbá Rọ́pò fẹjọ́ sun Àlíkìámọ̀ Mọmọdu Jógunómí, tí ó jẹ́ àgbà ìjòyè ogun Ìbàdan pe Abídogun wá bá ìyàwo òun lò pọ̀ lójú òun àti àwọn ẹbí òun. Èyí ló mú Jógunómí bèèrè ọ̀rọ̀ lọ́wọ́ Abídogun ìdí tó fi hu irú ìwà bẹ́ẹ̀. Jógunómí sọ pé níwọ̀n ìgbà tí ó ti jẹ́ pé Rọ́pò ló kọ́kọ́ dánrú èyí wò, dandan ni kí gbogbo ẹbí Bàbá Rọ̀pò fi ìlú Ìbàdàn sílẹ̀ fún òun.

Fọ́nrán gbọ̀n-ọ́ngbọ̀n-ọ́n ló tí Oyedokun dé ìlú Apòmù. Aólẹ̀ tí í ṣe ọmọ Akèyọ̀ ni ó fẹ́ tà á ní ẹrú, kí àwọn Ìlàrí Alápòmù tó gbà á lọ́wọ́ àwọn Ìjẹ̀bú olówò ẹrú (wo fíìmù). Lẹ́yìn tí ó gba ìdáǹdè tán ni ó di Babaláwo ní ìlú Apòmù tí ó fi ibẹ̀ ṣe àtìpó, kò padà sí ìlú Ọ̀yọ́ mọ́ níbi tí ó jẹ ìlú abínibí rẹ̀. Ọmọ ọ̀dọ̀ náà fi ọgbọ́n ṣe é. Bóyá ká ní ó ti padà ní ìgbóná gbooru, ṣé Aláàfin kò ní fi ìyà tí wọ́n fi jẹ ọmọ rẹ̀ ní Ápòmù jẹ́ẹ́ padà lọ́nà tó dógbín.

Bí a ti ṣe fi hàn nínú fíìmù *Àbẹ̀ní*, ìbìnú, ìwọ̀sí àti ẹ̀gbin máa ń mú àjèjì padà sí ìlú rẹ̀. Olóyè Bélò ló fi ìbínú lé ọmọ aṣọ́ loro rẹ̀ kúrò níbi ayẹyẹ ọjọ́ ìbí Àbẹ̀ní tí ṣe ọmọ tirẹ̀. Yàtọ̀ fún lílé Àkànní tí í ṣe ọmọ asọ́loro rẹ̀, ó tún gba iṣẹ́ lọ́wọ́ Bàbá Àkànní. Èyí ni Bàbá Àkànní rò papọ̀ tí ó fi padà sí orilẹ-èdè rẹ̀ ni Benin.

Jàǹbà tàbí àjálù burúkú máa ń tí àwọn kan ká. Bí a ti ríi nínú fíìmù *Àfọ̀njà,* Ṣọlágbẹrú di ará Ìlọ́rin nígbà tí ìlú rẹ̀ jóná. Níwọ̀n ìgbà tó sì jẹ́ pé òun ni ó wolé de Àfọ̀njá nígbà tí Aláàfin ṣígun fún un lọ sí Ìwéré èyí ló fà á ti Àfọ̀njà fi tulẹ̀ fún Ṣọlágbẹrú ní Ìlọrin. Bí Ṣọlágbẹrú ṣe di èrò Ìlọrin tán ló fara mọ́

Alímì ẹlẹ́sìn Mùsùlùmí, ó ṣe bẹ́ẹ̀ àṣà di méjì mọ́ ọn lọ́wọ́. A ó máa ṣàlàyé lórí èyí láìpẹ́.

**Ìwọ̀ká Onífọ̀nrán Òǹfà**

Ìrọ̀rùn ni Ìwọ̀ká onífọ̀nrán òǹfà bá dé. Kò sí ogun tàbí ọ̀tẹ̀ tí máa ń ṣí ni nídìí. Nínú fíìmù *Odùduwà,* a rí i pé ẹ̀wọn ni Odùduwà tẹ̀rọ̀ wá sí Ilé-Ifẹ̀. Ó débẹ̀ tàì débẹ̀ wọn fi jọba nítorí ìwà akin tí ó hù nípa síṣẹ́gun àwọn ogun Ìgbò. Nínú fíìmù *Odùduwà* yìí kan náà ni Odùduwà tí pàṣẹ fún àwọn ọmọ-ọmọ mẹ́fà tí ó kù pé kí wọ́n jáde kúrò ní Ifẹ̀ kí wọ́n lọ wá ilẹ̀ tẹ̀dó káàkiri. Àwọn ọmọ rẹ̀ sí ṣe bẹ́ẹ̀. Ìwọ̀ká fọ̀nrán òǹfà ni Ìfẹ̀ láàárin ọkùnrin àti obìnrin. Èyí hànde nínú fíìmù *Àbẹ̀ní* níbi tí Àkànní ti wá Àbẹ̀ní lọ sí orílẹ̀-èdè Nàìjíríà láti ilẹ̀ Benin.

Fọ̀nrán oǹfà ìmọ̀ ni ó mú Olóyè Bélò fi ìlú Èkó sílẹ̀ lọ́ sí Ìbàdàn láti lọ kàwé ni Yunífásítì Ìbàdàn, fọ̀nràn òǹfà ìmọ̀ náà ló gbé ọmọ rẹ̀ Àbẹ̀ní lọ sí ilé-iṣẹ́ ìwádìí olokoòwò Àgbẹ̀ Songhai, ní orílẹ̀-èdè Kútonú (*Àbẹ̀ní*).

Fọ̀nrán òǹfà ìgbafẹ́ máa bí ìwọ̀ká ìran ọmọ Yorùbá bí a tí ṣe rí i wò nínú fíìmù Àbẹ̀ní. Níṣe ni Ọ̀gàgú àti Lákú máa ń lọ́ gbafẹ́ ní Kútọnú ní ilẹ̀ Benin. Wọ́n sì máa ń lo ọjọ́ pípẹ́ níbẹ̀.

Ẹ̀wẹ̀, Ìwọ̀ká fọ̀nrán òǹfà ìwàǹípò aṣojú lórí àwọn ìlú àmọ́ nà náà wà. A rí àpẹẹrẹ yìí nínú fíìmù *Jógunómí* níbi tí Ajẹ́lẹ̀ Ìbàdàn ti ń jayé ọlọ́ba. Ó ń gba oko, ó sì ń gba ilẹ̀ káàkiri. Ẹni bá sọ̀rọ̀, ó dágun.

**Ipa Ìwọ̀ká lórí Àṣà**

A ṣe àkíyesì pé bí ogun tí ń tú ìràn Yorùbá ká tí àwọn mìíràn sì ń ṣí kiri, ni àyípadà ń dé ba àṣà wọn. Lára àwọn nǹkan tí àyipadà dé bá ni: èdè, ẹ̀sìn, ìwọṣọ àti ikini wọ́n.

Nínú fíìmu *Àbẹ̀ní* a rí i pé ìsọwọ́lèdè àti ìpèdè Ọ̀gàgú àti Lákú yàtọ̀ sí ti àwọn òbí àti àwọn ará ilé wọn yòókù tí kò fi ilú sílẹ̀. Wọ́n ń fimú sọ̀rọ̀ bí àwọn ará ilẹ̀ Àmẹ́ríkà. Nígbà ti Ọ̀gàgú àti Láku tún kọ́ èdè Faranse sísọ nígbà tí wọ́n dé Kótọnú ní ilẹ̀ Benin, àwọn alásè ilé ìtura kọ́ wọn pé ẹran adìẹ ni wọ́n ń pè ni *pùléè* ("poulet"). Ẹ̀wẹ̀, nígbà tí àwọn Sọlágbẹrú àti àwọn ọmọ Yorùbá tí wọn darapọ̀ mọ́ Álímì ti i ṣe ẹlẹ́sìn Mùsùlùmí, ní àwọn náà ti pahùn dà, tí wọ́n bẹ̀rẹ̀ sí ní lo àwọn àká ọ̀rọ̀ bí *Àwúsùbìláhì, Àláùákíbàrù, jàmáà, Wàláì-tàláì, Jálà-jàláílù.* Èdè Yorùbá wá ṣe bẹ́ẹ̀ di àmúlùmálà pẹ̀lú èdè ti Mùsùlùmí. Èdé Yorùbá wa ṣe bẹ́ẹ̀ di nǹkan adíkálà nílùú Ìlọrin.

Àyípadà tún bá ìgbàgbọ́ wọn gẹ́gẹ́ bí wọ́n ṣe pàtẹ rẹ̀ nínú fíìmù *Àfọ̀njá.* Ẹ̀sìn Mùsùlùmí ni wọ́n gbà tí wọ́n sì ń fa tẹ́súbíyù lọ́wọ́. Wọn kò bọ Ṣàngó mọ́ débi pé wọn yóò jorukọ mọ́ ọn Ẹ̀sìn tuntun tí wọ́n gbà tún fa sábàbí àyípadà bá orúkọ kúrò ni Àjàdí Àmàó àti Ṣàngógbìjà tí wọ́n ń jẹ́. Wọn kò jẹ́ gbogbo orúkọ Yorùbá yìí mọ́, nítorí pé gbogbo wọn ti kírun. Orúkọ tí wọ́n wá jẹ́ ni "Bélò, Bèlò, Bélò" gẹ́gẹ́ bí Àarẹ Ọ̀nà-Kakañfò Àfọ̀njá ṣe wí nínú fíìmù *Àfọ̀njá.*

Ẹ̀sìn Mùsùlùmí yìí kàn náà ló bí àyípadà ìwọsọ àwọn ọmọ Yorùbá tí wọ́n gba ẹ̀sìn náà. Wọ́n bẹ̀rẹ̀ sí wọ sòkòtò

nàǹgúdù. Wọ́n wá bẹ̀rẹ̀ sí ni wé gèlè. Ẹ gbọ ohun ti Ààrẹ̀ Ọ̀nà-Kakaǹfo Àfọ̀njá wi nínú fíìmù *Àfọ̀njá.*

| | |
|---|---|
| Ààrẹ̀: | Àjàdí, Àmàó, Ṣàngógbìjà gbogbo yin lẹ ti di ońgèlè. |
| Ṣangógbijà: | Ààrẹ̀ a ò jẹ́ gbogbo orúkọ wọ̀n-ọnnì mọ́, gbogbo wa là ti kírun. |
| Ààrẹ̀: | Oókọ wo lẹ̀ wá ń jẹ nísìnín o? |
| Ṣàngógbija: | Èmí ń jẹ́ Bélò |
| Àmàó: | Bélò náà ni |
| Àjàdí: | Bélò loókọ tèmi náà |

Kò gbọdọ̀ wa jẹ nǹkan ìyàlẹ́nu fún wá nígbà tí a ba gbọ́ tí Yorùbá bá sọ pe: Bélò pọ̀ ní Ìlọrin, wọn kò lóókọ mìírán tí wọn ń jẹ́ kọjá Bélò.

A tún wá ṣe àkiyèsí pé ọ̀pọ̀ ọmọ Yorùbá ni wọ́n ti pa àṣà ìkíni abínibí tì tí wọn ń ṣe àmúlò tí ìran mìíràn. Nínú fíìmù *Àfọ̀njá,* rí i pé níṣe ni àwọn ẹlẹ́sìn Mùsùlùmí tí wọ́n jẹ́ ọmọ Yorùbá bẹ̀rẹ̀ sí lóṣòó láti ki ara wọn dípò kí wọ́n dọ̀bálẹ̀ tàbí tẹ̀ kí ará wọn. Àmọ́ ní tí àwọn tí wọ́n jẹ́ àbọ̀dé Àmẹ́ríkà, dípò kí wọ́n dọ̀bálẹ̀ kí àwọn òbí wọn, níṣe ni wọ́n fi ẹnu kò àwọn òbí wọn lẹ́nu, tàbí kí wọ́n bẹ́ mọ́ óbí wọn bí i ọmọ ọ̀bọ. Ọ̀gàgú àti Lákú hu irú ìwá yìí sí àwọn òbí wọn.

## Ìkádìí

Nínú pépà yìí a yiri nǹkan wọ̀n-nnì tí ó ń bí ìwọ̀ká nípa síṣe àmúlò tíọ̀rì ìṣe-kárí-ayé. Ọwọ́jà ìṣe-kárí-ayé sì kan tíọ̀rì

ìṣàtakò-ìmúnisìn. Nípasẹ̀ tíọ̀rí yìí ni a fi mọ̀ pé ọ̀wọ̀ méjì gbòógì ni ó ń bí ìwọ́ká ọmọ ènìyàn lórí ilẹ̀ ayé. Àwọn náà ni fọ́nrán gbọ̀n-ọ́ngbọ̀n-ọ́n àti fọ́nrán òǹfà tí wọ́n jẹ́ gbédìígbédìí tí gbéni kiri.

Lábẹ́ ọ̀wọ̀ fọ́nrán gbọ̀n-ọ́ngbọ̀n-ọ́n tí ó gbe ọmọ Yorùbá ni ìmúnilẹ́rú, ìfipá-lé-ọmọ-onílẹ̀-nílé, ìṣaṣemáṣe, àti àjálù-ìbànújẹ́. Ṣùgbọ́n lábẹ́ ọ̀wọ́ fọ́nrán òǹfà, tí ó ń gbé ọmọ Yorùbá jáde ni a ti rí ìfnúfẹ́dọ̀ wọ̀lú kan yálà láti tẹ̀ ẹ́ dó tàbí darapọ̀ mọ́ àwọn ọmọ ìlú náà, ìgbafẹ́, ìfẹ́ àti ìmọ̀ wíwá kiri.

Ṣùgbọ́n ó hànde nínú pépà yìí pe oríṣìíríṣìí àyípadà ló máa ń de ba àṣà Yorùbá nígbà tí àwọn ọmọ Yorùbá ń ba wọ́ káàkiri. Irúfẹ́ àyípadà lè jẹ mọ́ ẹ̀sìn, èdè, ìwọṣọ, àti ìkíni. Yorùbá bọ, wọ́n ní: Bí ewé bá pẹ́ lára ọṣẹ, á di ọṣẹ. Nǹkan yìí ni a tàn-mọ̀-ọ́n pé o bí ìṣe adíkálà tí ó bá àṣà àti ìṣe Yorùbá.

Àwọn òye nǹkan tí iṣẹ́ ìwádìí tún fi lọ́lẹ̀ ni pé àwọn tí wọ́n bá ti wọ́ká lọ ilẹ̀ mìíràn máa ń fara gbọ́n-ọnni ìṣe, àṣà, ẹ̀sìn àwọn ilẹ̀ mìíràn. A sì rì àwọn àrítọ́kasí. Bí àpẹẹrẹ, a gbọ́ pé Iba Olúyọ̀le ti ilẹ̀ Ìbàdàn ni ó mú Eégún wọ ilẹ̀ Ìjẹ̀bú. Bẹ́ẹ̀ ni a tún rí i kà nínú ìtàn ilẹ̀ Ìbàdàn pé Ayọrinde Ajé tí í ṣe Òsì Balógun Ìbàdàn ló mú Egúngún Olóòlú wá sí ìlú Ìbàdàn láti Ìrùn tàbí Ọ̀gbàgì Àkókó. (Ogunniran 2000:329; Fatokun 2011:81). A tún rí i pé nípasẹ̀ ìwọ́ká ọmọ Yorùbá náà ni ayípadà ṣe ń bá ètò ìjórúkọ wọn, wọ́n ń jẹ́ orúkọ ẹ̀sìn. Ní ṣókí, nípasẹ̀ ìwọ́ká ènìyàn ni àṣà àti ìṣe ìran kan kò fi dúró lójú kan mọ́. Ọ̀rọ̀ wá di Ayé ń yí lọ à ń tọ̀ ọ́.

Ẹ jẹ́ kí a fi ìbéèrè kádìí pépà yìí: Ta ń mọ̀ bóyá nípasẹ̀ ìwọ́ká ni a fi ń ri àwọn ìlú kan tàbí àdúgbò kan tí wọn fi ń jórúkọ tó yí wọnú ara wọn? Àwọn orúkọ tó lè yára wá sọ́kàn ni: Ìjẹ̀bú-Ifẹ̀ ní ìpínlẹ̀ Ògùn, Ìjẹ̀bú-Jẹ̀sà ní Ìpínlẹ̀ Ọ̀ṣun, Ìjẹ̀bú Músin ni ìpínlẹ̀ Ọ̀ṣun àti Ìsàlẹ̀-Ìjẹ̀bú ni ìlú Ìbàdàn ni ìpínlẹ̀ Ọ̀yọ́. Àwọn ẹyà Ọ̀yọ́ kan tilẹ̀ wà ní Ìkẹ́rẹ́ ní ìpílẹ̀ Èkìtì tí wọn ń pè ní Ọ̀yọ́-Ìkẹ́rẹ́. Àbá ti a fẹ́ dá ni kí iṣẹ́ ìwádìí sì tẹ̀síwájú ní agbọn yìí.

## Ìwé Ìtọ́kasí


Adeleke, Duro (2011). *Lẹ́yìn ìtàn Àròsọ D. O. Fagunwa Márààrún, Ewo ló kú?* Ibadan: DB Mortoy.

Akintoye, S. Adebanji (2010). *A History of the Yoruba People* Dakar: Amalion Publishing.

Babalọla, Adeboye (2001). *Àwọn oríkì orílẹ̀ Mẹ́tàdínlọ́gbọ̀n* Ikẹja: Longman Nigeria, Plc.

Falọla, Toyin (2012). *Atlantic Yoruba and the Expanding Frontiers of Yorùbá Culture and Politics* Ibadan: J. F. Odunjọ Memorial Lectures.

Ogunniran, Lawuyi (2000). *Ìbàdàn Mesiọ̀gọ̀: Kìnnìún ilẹ Yorùbá (1829-1893).*

Okome, Mojubaolu O. (2005). "The Antinomies of Globalization" ninu Olufẹmi Vaughan, Marcheta Wright and Charles Small (olootu), *Globalization and Marginalization,* Ibadan: Sefer.

**Fíìmù Àmúlò**

*Àbẹ̀ní*, (2006) Mainframe Film and Television Productions (Òpómúléró).

*Odùduwà* (2000) Òjójolú Films Ltd.

*Jógunómí*, (2003) Anike Obot Films.

*Àyàn Àgalú* Funmi Àkànkẹ́ Onisinnima àti Razol Entertainment.

*Àfọ̀njá* (2002) Remdel Production.